# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 711 THURSDAY, JUNE 4, 1964 (2D)


## Fani – Kayọde Lọ Si Ilu Oyinbo

IKẸJA:– Ni deede agogo mejọ alẹ ọjọ Aiku ti ise ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi ni Oloye Fani-Kayọde, Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ ati igbakeji Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ba ọkọ Ofurufu kuro ni Ibudo ọkọ ofurufu Ikẹja lọ si ilu Oyinbo.

Onirohin wa fi ye wa pe awọn enia diẹ lo sin Oloye Fani-Kayọde de Ibudo ọkọ Ofurufu ki o to lọ ni ọjọ na.

Irohin fi ye wa pe ohunti Oloye Fani – Kayọde nlọ ṣe ni ilu Oyinbo ni lati lọ da ile iṣẹ Asoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pọmọ ti ile iṣẹ Asoju Apapọ Ijọba

Nigbati Ejongboro bere lọwọ Oloye Fani-Kayọde pe, ni igbati o fẹ pada wale, Oloye Fani-Kayọde ṣe alaye pe on ko le sọ, sugbọn ti on ba gbọ pe rogbodiyan ṣẹlẹ ni asiko ti Dokita Okpara nṣe ibẹwo yi, LẸSẸKẸSẸ ni on yio yara tete sare wale, ṣugbọn ti ko ba si ija, yio to ọjọmẹta ki on to de.



Oloye Fani-Kayọde

## Ko Ha Ni Si Ina Ati Omi Loni L'eko Bi ?

# IGBA-IRETI AWỌN OṢIṢẸ FỌ L'ORI APATA !

EKO :— Gbogbo awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ lo dorikodu bi ewe ọgẹdẹ ti gbogbo ile si pa lọlọ nigbati Ọgbẹni J. C. Ọbande, Minista alamojuto eto idasilẹ fun Apapọ Ijọba Naijiria nsọ fun awọn aṣiwaju ẹgbẹ Oṣiṣẹ pe Apapọ Ijọba Naijiria ko ni le fi pọnuu mẹta kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ bẹni owo-ọya oṣu meji pere ni Ijọba yio san dipo owo oṣu marun ti Igbimọ Morgan sọ pe ki Ijọba san fun awọn oṣiṣẹ.

Lẹhinti Ọgbẹni Obande ti sọ ọrọ yi tan ni o wa ṣe alaye fun gbogbo awọn oṣiṣẹ ti o wa ninu ipade na ni owuro ana pe Apapọ Ijọba ko faramọ gbogbo ohun ti Igbimọ oluwadi na pala-



Ọgbẹni L. L. Boral

ṣẹ fun Apapọ Ijọba latiṣe oni ṣugbọn Apapọ Ijọba tise gbogbo awọn atunṣe ti o tọ ti osi yẹ si igbimọ oluwadi na.

Nigbati oti ṣe alaye na tan ni o wa pin iwe pẹnpẹ pẹnpẹ funfun ka eyiti ise ipinnu ti Apapọ Ijọba ṣe le gbogbo awọn asiwaju ẹgbẹ na lọwọ

Iwe na ṣe alaye bayi pe, "Lẹhin igbati Ijọba ti ka iwe na tan pẹlu akiyesi lori Abayọri Igbimọ na, Ijọba ri daju pe, ohun ti Igbimọ na sọ pe ki Ijọba o ṣe ko le rọgbọ.

Ti Ijọba ba tẹle ohunti Igbimọ na sọ, yio, mu aibalẹ ọkan wa fun gbogbo awọn ara ilu.

Igbimọ oluwadi na ṣe iwadi rẹ lori awọn ti o njẹ onjẹ atata ninu ile wọn Bẹni ki iṣe gbogbo awọn oṣiṣẹ ni o njẹ onjẹ atata ninu ile wọn.

Nipa pe ki awọn oṣiṣẹ o ma a jẹ iru onjẹ bayi ni Igbimọ oluwadi na ṣe ṣe ipinnu pe ki Ijọba fi pọnun mẹrindinlogoji kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ ni ọdun kan.

Ohun yowu ti o ba tilẹ mu Igbimọ oluwadi na sọ iru eyi, ki o si kọ iye owo oṣu ti Apapọ Ijọba ti nsan tẹlẹ fun awọn oṣiṣẹ.

Ijọba ko ni le san iye owo ti Igbimọ na paṣẹ fun Ijọba lati san.



Alhaji Adebola

Gẹgẹ bi Igbimọ na ti pa laṣẹ fun Ijọba lati ṣe, ti Ijọba ba tẹle imọran na, iṣẹ owo Aje orilẹ ede yi le forisan pọn lojiji.

Bi Ijọba ba gba lati ma san iye owo ti Igbimọ palaṣẹ yi awọn oyinbo onisowo ati onisẹọwọ kekeke ti nwọn da iṣẹ silẹ fun ara wọn ko ni le san iye na fun oṣiṣẹ wọn deede.

"Bi Apapọ Ijọba ba san owo na, ti nwọn si pa laṣẹ pe ki gbogbo awọn Oyinbo onisẹ ọwọ ki o ṣe bẹ gẹgẹ fun awọn oṣiṣẹ wọn pẹlu ipa eto na le yọrisi abamọ ni igbẹhin nigbati awọn onisowo ba san owo fun bi osu diẹ ati awọn ti o da iṣẹ ọwọ wọn silẹ, nwọn le ma a da awọn oṣiṣẹ wọn duro lẹnu iṣẹ nigbati agbara wọn ko ba ka iye owo ti ijọba sọ pe ki nwọn ma a san fun awọn oṣiṣẹ wọn.

"Nigbati o si jẹ wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ Ile iwe ti nwọn ṣẹṣẹ jade ti nwọn ko ti ri iṣe ṣe, ti Ijọba nwa ọna lati din arun airiṣẹṣe ti o wa ni ilu ku.

Nipa ṣiṣe bayi, o tun le mu ki iye awọn enia ti ko ri iṣẹ ṣe o tun pọ si ni arin ilu, dipo eyi ti o yẹ ki nwọn o ma a dinku.

"Ijọba gbọdọ ṣe pẹlẹpẹlẹ lati ṣe ohun ti o le ba iṣẹ owo Aje orilẹ-ede yi jẹ bi Ijọba ba le san iye ti Igbimọ na da nimọran, o yẹ ki arati awọn onisowo ti nwọn nṣe iṣẹ ara wọn, ti ko si ni le ṣe ohunti Ijọba ba ṣe fun awọn osiṣẹ ti wọn.



Ọgbẹni Gozochi Nzeribe

Nipa sisan owo yi ti Igbimọ na da ni imọran, ti apa awọn onisowo na ko ba le san an, awọn miran le ti itori rẹ ti ile iṣẹ wọn tan patapata ti nwọn o si pada lọ si ilu wọn.

Ijọba ti nṣe gbogbo eto ti o wa ni agbara wọn lati ri wipe gbogbo awọn Oyinbo onisowo ni o le ma a gberu lati igba de igba.

Bi iru nkan ba wọnyi ba ṣẹlẹ ti awọn Oyinbo na ba salọ, eyi yio mu eto airiṣẹṣe pọ ju bi o ti ṣe yẹ lọ.

Bakanna ẹwẹ ni Apapọ Ijọba ko ni le san iye owo ti Igbimọ Morgan sọ pe ki nwọn san fun awọn oṣiṣẹ nitori eto idagbasoke iṣẹ ọdun mẹfa eyi ti Apapọ Ijọba gbe siwaju ni asiko yi.

Ohun ti Apapọ Ijọba ngbero lati ṣe ni asiko yi fun idagbasoke ilọsiwaju orilẹ-ede yi ni lati ṣe atunṣe gbogbo awọn oju ọna ti awọn ọkọ reluwe nlo, oju titi ti ọda yio wa ni gbogbo lorilẹ-ede yi ati eto abo

WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## E Ba Wa Mojuto Onjẹ Wa !

Olotu, Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye lati kesi Ijọba Ibilẹ ilu Eko lati yan oluwadi ki o ma wo awọn wole-wole ti o nṣiṣẹ ni agbegbe Mushin.

Awọn wole-wole ti o nṣiṣẹ ni Mushin ko ṣiṣẹ wọn bi o ti tọ ati bi o ti ye, eyi ti nwọn ko ba fi kilọ fun awọn ti o nta onjẹ nipa pe ki nwọn ma jẹki gbo-gbo nkan ti nwọn nlọ wa ni mi mọ, ti nwọn ba de ọdọ awọn olonjẹ nwọn ko ni sọrọ tabi ki nwọn fun iya olonjẹ ni imọran ni imọtoto, ti nwọn ba de ibẹ nwọn o kun lọ lasan laiko ni sọ ohunkohun, iru eleyi ko si dara rara.

Nitori idi eyi, mo bẹ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko lati yi awọn wo-le-wole yi pada, ki nwon si yan awọn miran si ilu Mushin.

Emi ni,
Adekunle Adeniji.

MUSIN.

## Ajẹgborodagba Nkọ ?

Mo ki Olotu ẹ ku iṣẹ o, Olu-wa yio ma ṣe amọna yin o, inu mi iba dun pupọ ti ẹ ba le gba mi ni aye lati sọ ẹdun ọkan mi fun yin, boya ẹo ran mi lọwọ nipa ọrọ na.

Ohun ti o mu mi kọwe na ni nipa Ọgbẹni wa Ajẹgborodagba ti a ti ma nri ọrọ rẹ ku deeda ti a ko ri ka. beni ọrọ Ọgbẹ-ni wa yi na kun fun ọgbọn o si tun ma nfun wa ni ọpọlọpọ imọ ran paapa awọn ọmọ ile iwe ni-torina, a fẹ ki Olotu ba wa ṣe iwadi nipa okunrin yi boya o ti ku ni tabi o si mbẹ. Orungbẹ Ajẹgborodagba ngbẹ awa onka-iwe Irohin Imọlẹ o.

Lakotan ọrọ mi, mo lero pe Olotu yio tete ba wa ṣe eto yi. Ẹ ku iṣẹ o.

Emi ni,
J. A. Ayandeji,

EKO.

## Wundia Egiọyọpo, o Di Ọwọ Nyin

Oloru ẹ gba mi ni aye diẹ ni-nu iwe nyin Oloyinmọmọ lati ba awọn wundia ilu Egiọyọpo sọrọ atata lori iwa oju kogbe ibikan ti nwọn nhu ni asiko yi a wa yi iwa na ko dara to bẹ ni ko si ba igba mu.

O di ti iwa awọn ọmọbinrin na lati mọ fẹ awọn ọmọ ilu wọn mọ, a ri awọn awọn alejo ati ara ilu miran.

Awọn asiwaju nyin ko hu iru iwa ti ẹ nhu yi rara, nitoripe ẹsin ti iwaju ni ti ẹhin lati wo sare. Ẹnyin ko ṣe bẹ rara, iwa ti o wu nyin ni ẹ nhu si ara nyin.

Ki ẹ si tun sọra fun iwa oju-kokoro ti o nba alafia ati anfa-ni nyin jẹ ti o si nfa ogun ẹlẹ-sinni ti ẹ si nbi ọmọ ti ko ni baba jọ.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni,
Amọdu

Igbaja

## A Nfẹ Ile-Iwo-san Ni Ajassẹ-Ipo

Mba sọpe bi Olotu ba le gba mi laye lati ba kesi ijọba Ipinlẹ Ariwa ki nwọn o jọwọ kọ ile iwosan nla fun ilu wa Ajassẹ-Ipo, nitori aiko si ile-iwosan yi njẹ wa ni iya o si nfa ọpọlọpọ iku ojiji nitori ti enia ba nṣe aisan, o ma ngba to wakati mẹta, eyi asi ma fa ki awọn alaisan miran ku ki nwọn to de ile-iwosan ilu Ọfa.

Inu wa yio dun pupọ bi ijọba rere ti Ibilẹ Ariwa ba tete kọ ile iwe-iwosan fun wa, nitoripe awa ara ilu Ajassẹ-po ki nfi owo ori jafara rara.

Ao ma reti yin o.

Emi ni,
Seudu Ọsọlọ.

AJASSẸ-IPO.

## A Nfẹ Ẹgbẹ Imọ-lẹ Aiye Ni Oshogbo

Olotu,

Pẹlu iteriba ni mo fi bẹ yin pe ki ẹ jọwọ gba mi ni aye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi Alaga, ati akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ki nle sọ ẹdun ọkan mi fun awọn Oloye mejeji yi.

Ẹ dun ọkan mi na ni nipa ti ẹgbọ Imọlẹ Aiye, a nfẹ ki nwọn da ẹgbẹ Imọlẹ Aiye silẹ ni Osho-gbo nitori ki awa ọmọ Yoruba nilẹ yi na le di ọmọ ẹgbẹ nitori gẹgẹbi ere ẹgbẹ na, fun ilọsiwaju ati idagbasoke ti ẹgbẹ na nwa fun awa ọmọ Yoruba.

Inu mi yio dun ti ẹba le da ẹgbẹ na silẹ ni Oshogbo nitori gbogbo igba ni awa na ma nkawe Irohin Imọlẹ ti a si ngbọ Irohin ẹgbẹ na nigbagbogbo paapa nipa oriyanjiyan ti nwọn ṣe laipẹ yi.

Emi ni
Ọlaniyi Adekọya

OṢHOGBO.

## Eyi Ko Ye Mi

Olotu inu mi yio du pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti nta bi akara gbigbona lati bere ọrọ ti ko ye mi yi lọdọ awọn ọlọgbọn ati oloye ti nka iwe nyin lojojumọ ibere na jẹ nkan ti o sa nsumi loju inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le la ọrọ na ye mi.

Nigbati mo fẹ ṣe igbeyawo a lọ si ile-ẹjọ lati lọ ṣe igbeyawo (Court Marriage), a si fi ọwọ bọ iwe pe, ao ni kọ ara wa silẹ titi ti iku yio fi ya wa.

Ẹjọwọ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ kini ki nṣe si ọrọ na?

Mo dupe fun aye ti ẹ gba mi iwaju ni ọpọ ẹbti nyin yio maa resi

Emi mi
R. A. A. Abikoye


# SEDO — PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn alera tabi amedi wọnyi ba nyọ ọ lẹ-nu lode ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbaku-gba, A'efọ, Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi ada-rin egbo ekusẹ tabi ekusẹ tabi lapalapa, Ela tabi ara sisu, Akọ, inarun ati orişirişi orun "Ara" miran gbogbo





Gbiyanju lati da egbogi tiun awon ara Ilu Tatanbu bulu ṣe ti nwọn npe ni "PAYAL" wb larin ọjọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn elomiran pẹlu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn rọbirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowy egbogi arun arun ara haunhaun ti ko si ṣiṣe ye meji niru eleyi si yatọ patapata si awon ẹgẹ-rẹm ti adimọwọ ti wọn nta kakiri igboro ati ni agbereko ẹgọ ba pẹlu Orisi meji rẹ lo wa. Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbi fun SEDO PAYAL yi ni ṣọbu awọn:

PILENAB MIXTURE,

Egboigi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijedi bi ako gbọnsẹ dede ba nyọ lẹnu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printed Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.

# Awọn Ọmọ Egbẹ Oduduwa Ṣe Ajọdun

Igbimọ alabẹsẹkele ti ẹgbẹ ọmọ oduduwa ṣe ajọdun nla kan ni ọjọ Aiku ọjọ kẹtadinlogun oṣu karun ritu ọdun yi ni Eko.

Ẹniti o ṣe alaga ipade na ni Oloye M. A. Ajasin, ẹni ti o jẹ olori ẹgbẹ na, awọn ipinnu ti aṣe ninu ipade na ni wipe gbogbo ẹka ẹgbẹ ọmọ oduduwa ni lati ṣe iranti Oduduwa ni ọjọ Iṣẹgun ti ṣe ọjọ keji oṣu kẹfa (2/6/64) ti a wayi.

Gbogbo ẹka ẹgbẹ na gbọ dọ ṣe oriṣiriṣi ariya ki awọn onigbagbọ lọ dupẹ ninu ile Ọlọrun wọn ni ọjọ Aiku tiṣe ọjọ keje osu kẹfa (7:6:64), ki awọn ọmọ ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ti ọjẹ Musulumi lọ dupe ni Mọsalaṣi ni ọjọ karun osu kẹfa ọdun yi (5/6/64) ni gbogbo ilu Eko

Nwọn si yan Alhaji Y. K Yakubu ni akọwe Apolowo ẹgbẹ.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Maṣe ba ẹnikan ji yan, nitoripe bi oba ṣe bẹ, iwọ yio ri ohun ti oju rẹ ko fẹ ri, mura ki o le, iranlọwọ airotẹlẹ yio de si ọ owo le tẹ ọ lọwọ loni.

PISCES (Feb 21 – Mar) Ire wa fun gbogbo ohun ti o ba ṣe loni fun ara rẹ, owo yio tẹ ọ lọwọ loni.

Aries (Mar 21 April 19) Iṣẹ yio pọ ni ṣiṣe fun ọ loni maṣe ko awọn alejo pupọ mọra ma si ṣe ileri ohun ti apa rẹ koka.

TAURUS (April 20–May 20) Ohun kan ti o ti nru ọ loju, eyi ni akoko rẹ lati fi opin si ati ẹyiti o ngbero lati da silẹ. Oni dara fun ọ lati lọ ki awọn ọrẹ rẹ ki o si kọwe si okere

GEMINI (May 21–June 21) Ọrọ ara rẹ dara, iṣẹ si mbọ wa tẹ ọ lọwọ. Irin ajo mbẹ lẹsẹ rẹ. Bi o ba si jẹ wipe ki o sare lọ pe kabọ ko buru Bi o ba ta tẹtẹ iwọ jẹ pupọ. Sọ ọrọ ẹnu rẹ ni sisọ.

CANCER (June 22- July 23) Orire airotẹlẹ *yio* pọ fun ọ loni, sa ṣẹjẹjẹ wahala na ko ni pẹ kuro, Oni lọjọ ti o dara lati rin faaji lọ sode,

LEO (July 24-Aug 22) O ngbero lati da iṣẹ kan sile nṣe ni ki o dupẹ lọwọ ọrẹ ti o jẹki nkan na ṣeṣe iwọ yio ba awọn ti o nifẹ si ọrọ rẹ pada

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Eyi ni akoko ti o ni lati fi suru ko ọrọ kan loju. Irawọ rẹ yio fi ye o gẹgẹbi o ti ni lati ṣe ọna rẹ Ipade aṣiri ati ojutikan yio jade si ọ yio si ṣe ọ nirere

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Ọrọ ikilọ ti nwọn kọ ọ pe ki o maṣe da si ọrọ kan rere ni ọrọ na awọn ọrẹ rẹ yio ṣe iranlọwọ fun o doba.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iṣẹ rẹ yio ni irẹwẹsi diẹ, o yẹ ki o gbatẹgun lẹ silu miran tabi ki o ni ọrẹ titun, lọ wa isimi pelu olufẹ rẹ pẹlu.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ranti ero kan ti o ti ngba nigba kan, oni li ọjọ ti o dara lati mi gun si.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Ọjọ imura silẹ ni oni jẹ o si ni lati ṣe girigiri si ọrọ na iwọ yio ṣe orire la rin ẹgbẹ.


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

*FUN*

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE–IṢẸ–ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16 Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO *PỌKU* NI A *SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo k o ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la okun losan tabi lora tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn alera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbura

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lago-
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba

# 'Ẹranko-kẹranko Enia-kenia'

Lati Ọwọ R. A, DUNMOYE OKEYA,

Inu mi yio dun bi Olotu ba le jẹ ki itan mi yi jade ninu iwe rẹ Itan na kan fun Ọgbọn ati oye Ọpọlọpọ awọn ti o ka itan mi ti mo kọ gbẹhin–OṢIKA DA' LẸ O BA 'LẸ LỌ (Itan Ogundele ati Adeniyi) ni wọn nkọ iwe si mi wipe awọn nreti itan aladun miran Nitori idi eyi mo ro wipe ẹ o gbadun eleyi na.

Ni akoko kan ni ilu Eko yi na ni adugbe kan ti nko fẹ daruko rẹ, arabirin kan wa ni ile Ọkọ rẹ Arun pọ ni ara rẹ, o ndoko on sofofo Ọmọ Ọkọ rẹ eke ṣiṣẹ ko jẹ ko roju gbo ti ara rẹ, Ṣugbọn arun pataki ti o nṣe ni arun Ọmọ bibi. Lati bi ọdun kẹ wa to ọkọ rẹ ti gbe silẹ, owọn na owo na ara, sugbọn inu ajere ni gbogbo rẹ nbọ si.

Lẹhin igbati ọkọ rẹ ti sa jo titi ti o fẹrẹ su ni o ba mu Obirin yi lọ si Baba Onişegun kan ti ki ise ti. Baba Onişegun gba Owo, o gba ẹran, o si gba ọpọlọpọ nkan Obinrin yi wa fi ile Baba lawo na şe ile a gbe ibẹ fun Ọdun kan.

Nigbati ọdun keji npari lọ, baba onişegun na wipe arabinrin yi fẹ ba işẹ on jẹ, nitoripe ẹnikan ko wa si ọdọ on lairi ọmọ bi ri. Baba yi wa nwa ọna ti on yio fi le lọ kuro lọdọ on. Ni owurọ kutu ọjọ kan, o de arabinrin yi, o ni on ti şe ayẹwo ifa on, ti o ba fẹ ri ọmọ bi, ti ọlọmọ ba npe ọmọ fi na ma pe ti rẹ. O ni odu ti o yọ ni wipe ki o lọ wa nkan kekere mẹta wa. awọn na ni "Igikigi Ẹran kẹrankokẹranko, ati Eniakenia"

Arabinrin yi lọ ile o ko oro fun ọkọ rẹ ohun ti Baba onisegun ni ki on şe Ọkọ ni on yo sa agbara on, nitoripe ọrọ ti ọmọ si ndun lọkan pupọ. Gbara ti o ji lowurọ ọjọ keji o mu ada rẹ, o gba ẹhin kule lọ.

Bi o ti de ẹhinkule, o mu ada rẹ o fẹ lati bẹ igi lapalapa. Lapalapa bere ohun ti on şe fun lowurọ kutukutu bayi, Ọkunrin yi sọ fun wipe on wa igikigi ni, Lapalapa ni on ki işe igikigi, O sọ fun pe ti ẹhin ba nyọ ọmọ rẹ lẹnu, omije ti o ba ro ni ara on ki o kora kan an si, were ni ehin ọmọ yio fi si lẹ, Lapalapa sọ fun ti o ba nwa igikigi afomọ ni ki o lọ ja nitoripe on ni ko kọ ibi kan lati fo mọ. Bayi ni ọkunrin yi ri igikigi ti o ti nwa.

O tun mu ọfa rẹ o nwa ẹranko kẹranko lọ, Bi o ti fẹ jade ni o ri ẹiyẹle o fẹrẹ pa. Ẹiyẹle bere nkan ti on şe. Arakunrin yi sọ fun wipe on wa ẹrankokẹranko ni, ni Ẹiyẹle yi wi fun pe ti o ba da on si, on yi pa ọpọlọpọ ọmọ, ni eyi ti arakunrin yi le ko lọ si ọja lọta, ninu eyi ti yio ri owo gọbọi. O sọ fun ti o ba nwa ẹrankokẹranko ki o wa adan lọ, nitoripe adan ni ko şe ẹiyẹ ti ko si şe ẹranko ati wipe iwa rẹ ko ba ti awọn ẹranko yoku mu Bayi ni ọkunrin yi tun mọ ẹrankokẹranko ti o'nwa O wa ku eniakenia.

Arakunrin yi gbẹru o de arin ọja nibiti orişirişi enia bi orişi padora wa. O ronu owo yika ko mọ iru ẹniti on le ki lọrun mu lẹ ki on lọ mu fun baba onişegun. Bi o ti nro eyi lọwọ, ori were kaa ti o joko jẹjẹ ni ti rẹ ni o ba ki lọrun on mu lọ.

Were bere ohun to de.

Ọkọ iyawo yi sọ fun wipe ko si nkankan ju wipe on wa enia kenia lọ

Were sọ fun wipe on ki şẹ eniakenia ori enia bi rẹ na ni on şe, ọmọ araiye lo sọ on di bi on ti şe wa yi.

O wa juwe eniakenia ko arakunrin yi. Oni ti o ba nwa eniakenia nşe ni ki olọ si ibiti wọn ba şe nkan ariya gẹgẹbi iyawo gbigbe ọmọ kiko. Ẹnikẹni ti o ba ri ni iru ibiti wọn ba nfi yọ ayọ bayi ti o wa lọ da ija silẹ, tabi olọ ja, on ni ki ora mu Eleyi ni ENIAKENIA.

Ẹnyin ara mi ti o ka itan yi, pataki ohun ti mo fẹ ki a fi kọ ọgbọn ni itumọ Eniakenia ọpọlọpọ wa ni o ti nlo ede yi ni ilokilo.

Ko to, ko si yọ, bẹni ko dara fun ọmọ enia rere, ki o ma lọ ba nkan jẹ, Ẹniti a bi re ki ria loru Awọn ẹlomiran ti wọn ba ti de ibi ariya kan, ọgbọn ki wọn daru ni wọn o ma wa. Iwa bẹ ko dara. Ẹni ba si hu iru iwa yi ni a npe ni ENIAKENIA.

Ọmọ Dunmoye nre ile, laipẹ.

Ẹ o tun mọ ri ọwọ mi.

---

# E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojoojumọ

---


## AFRICAN SPECIAL

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN, KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 711 THURSDAY JUNE 4, 1964 (2D)


## Alhaji Kan Lu Ore Re Ni Jibiti

JOS:- Gbeg ide gbina ninu Ile ejo kekere Jos nigbati awon olopa mu odaran Alhaji kan, Alhaji Ahamadu Raji wa siwaju adajo fun esun jibiti ati ole jija ati lati fi ipa gba ohuni ni omonikeji ni ojo Aje ti ise ojo kini osu yi.

Olopa ti o ba odaran na sejo se alaye fun Ile ejo pe, odaran na lo gba ponun medogbon (£25) lowo omo-ekose moto kan, ogbeni Sebo Bukuru, lehin ti o ti se apejuwe ara re gege bi oga Agba kan ninu ile ise awon alase ti nfun awon onimoto ni iwe ase moto.

Lehin na ni odaran Alhaji na wa so fun ogbeni Bukuru pe ti o ba le fun on ni ponun medogbon pere on yio fun ni iwe ase (Licence) lati ma a wa moto loju ona.

Olopa na tun se alaye pe lekese ni ogbeni buruku sare lo wa poun medogbon fun nigbati o si gba owo na tan ko fun on ni iwe na mo nigbati ogbeni Buruku si bere pe bi iwe na ko ba le bamu mo ki o ba on mu owo, odaran na ko lati fun ni owo re pada.

Lehin alaye si ni adajo ba pase pe ki odaran Alhaji na lo fi ewon osu meji jura.

# Igba—Ireti Awon Osise Fo L'ori Apata !

### Lati Oju Ewe Kini

fun ile Naijiria.

"Beni Ijoba nse eto ati da opolopo ile ise sile kakiri orile ede yi, eyiti yio se anfani fun olukuluku enia.

"Lati se gbogbo awon nkan wonyi, awon ara ilu gbodo ni emi isera eni lati jeki gbogbo awon eto na o le moke lonakona.

Ki Ijoba si to le se awon ise ti o wa niwaju won ni aseyori, owo osu awon osise gbodo je eyiti yio fi idi mule sinsin pelu otito inu ninu eyi ni agbara fun awon onisowo ati awon osise arawon ti da ise sile lati le maa san iye owo ti agbara won ka fun awon osise won ni asiko.

Bi Ijoba ko ba se akiyesi gbogbo awon ohun ti o diromo oro na lorun, ayorisi eru ekunwo na le tun fi kun iye awon enia ti ko ri ise se nwon rin kakiri

Bakana ni Ijoba tun wo odi egbe keji pe, ti Ijoba ba le gba iyeti Igbimo Morgan so pe ki Ijoba san fun awon osise, gbogbo awon nkan bi onje ti awon Obierin ora loja ni yio gbe owo lori, ti awon oloja yio si tun fi owo kun owo oja won.

Ijoba si tun wo awon egbe ti nwon ko gba ekunwo owo osu ni ori oran na yio ta ju, orun yio si iwo won ti a ba si da awon enia ti o ngbe orile ede yi si ona merin, ida meta ni awon agbe ati awon ti o nsise ara won, ida kan yo ku ni awon osise abe Oba

Onirohin wa ran wa leti pe, ni ojo Isegun tisise ojo ketadinlogbon osu yi ni Apapo Ijoba gbe Irohin abayori iwadi ekunwo osu awon osise eyi ti Igbimo Mogan se jade.

Ninu abayori irohin ekunwo osu na Igbimo na so pe eniti o ba ngba poun Orun dinrinwo ponun (£318) ni odun kan ki Ijoba fi poun merindinlogoji (£36) kun owo won. Eyi ni pe eniti ngba ponun merindinlogbon (£26) ki Ijoba ma san ponun mokandinlogbo (£29) fun won ni ososu.

Awon ti nwon ba ngba poun mokandinladota (£49) ki Ijoba fi ponun kan kun owo won losu ki nwon si maa gba adota (£50) lososu.

Igbimo na so pe, gbogbo awon osise ti owo osu won ba ti koja adota (£50) ni osu kan ki Ijoba mase fi owo kun owo osu won, nitoripe owo ti nwon ngba losu to won na di ipari osu.

Igbimo na pase pe, ki Ijoba o lo san owo oya fun awon osise lati osu kewa odun ti o koja yi, eyi si je osu mejo ti awon osise yio gba owo re, sugbon awon ti owo osu won ba koja adota ponnu ni osu kan ko ni gba ninu owo oya na.

Bakanna ni Igbimo na tun pa lase pe, ki Ijoba ma fi ponun mejila (£12) bere fun awon lebira ni Eko ati agbegbe re.

Igbimo na tun pase pe ki Ijoba mase san owo fun awon osise, sugbon ki won ma san owo osu fun gbogbo awon osise.

### OWO—OYA

Sugbon ninu Iwe ti Ijoba fi sode ni ana, eniti Igbimo na so pe ki Ijoba fun ni eknuwo ponun meta (£3) Ijoba so pe ponun kan abo (£1: 10/-) ni awon le fi kun fun won ni osu.

Eniti Igbimo na so pe ki Ijoba fi ponun meji kun owo osu won Ijoba fi ponnu kan (£1) kun fun won Eniti Igbimo na ni ki Ijoba o fun ni ponun kan (£1) Ijoba fun won ni sile mewa (10/-) ni Ososu,

Bakanna ni Igbimo oluwadi na so pe ki Ijoba o san Owo oya Osu mesan fun awon Osise, eyi ni lati Osu kewa Odun yi titi de Osu kefa Odun yi, sugbon Ijoba so pe Owo-oya Osu meji pere ni Ijoba yio san.

Lesekese ti Ogbeni Obande soro tan. Oniwe irohin wa Ejon'gboro, fi ye wa pe, gbogbo awon Osise lo binu jade.

Ninu Oro won ni ale ana, gbogbo awon Osise ni nwon so pe awon ko ni sise ni Owuro yi, gbogbo awon ni nwon yio da ise sile. ti awon o si duro pa si ile ise awon.

Irohin fi ye wa pe gbogbo awon osise ise Elertiriki yio da ise sile ni owuro yi, ko si ni si ina ni gbogbo Naijiria ni oni.

Bakanna ni awon onise ero-omi so pe awon yio da ise sile ni owuro yi, awon ko si ni sise.

Awa oniwe irohin Imole wa kesi gbogbo enyin ara ilu lati tete lo pon omi ti eo ma a lo sile ki awon enia na o to le pada si enu won.

Bi awon enia na da ti se si ni oni eo ma a gbo ninu iwe wa ola.


## Egbe Omo Oduduwa

EKA — EKO

Eka egbe Omo Oduduwa Eko yio se Ajoyo kan pataki ni Ojo Jimo ti ise ojo karun ninu Osu June 1964 yi ninu ile Sinima Corona ni Ita-Faji ni dede ago-merin irole (4 p. m.)

Ki ese Okunrin ati Obinrin Omo egbe Oduduwa pe sibi Ajoyo na.

J. PRATT
AKOWE EGBE OMO ODUDUA
EKA - EKO



## Iyipada Ile Ise

Eyi nilati kede fun awon Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti lo si Ilu Itire ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Enikeni ti o ba fe bawa ra Iwe tabi Turari Ajebidan e kowe si ile itaja wa ni Nomba 1, Ishiba Street Odo

**Apejuwe Ile Ise Wa**

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itire Via,
Suru Lere, Yaba



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21958
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (4/6/64)